

# Jẹ́ Ká Kàwé

Kíláàsì 1

Sáà 1 – 3

Ìwé Akẹ́kọ̀ọ́

Yorùbá

USAID FROM THE AMERICAN PEOPLE

THE INITIATIVE

# Jẹ́ Ká Kàwé

**Ìwé Akẹ́kọ̀ọ́**

**Kíláàsì 1**

**Sáà 1 — 3**

Yorùbá

This early grade reading material for primary teachers and pupils in Nigeria is made possible by the support of the American people through the United States Agency for International Development (USAID) under the The Initiative program (Contract Number AID-620-C-15-00002).

First edition, 2021

Rights and permissions

The text and illustrations in this work are licensed under the Creative Commons Attribution 4.0 International License. To view a copy of this license, visit http://creativecommons.org/licenses/by/4.0/. Under the Creative Commons Attribution license, you are free to copy, distribute, transmit and adapt the work as long as you attribute or credit the original author or illustrator. In the case of this book use the following attribution language: “Developed under the USAID funded The Initiative program and licensed under the Creative Commons Attribution 4.0 International License.”

---

Ìwé kíkà fún àwọn èwe tí a ṣe àgbéjáde rẹ̀ fún àwọn olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní Nàìjíríà wáyé pẹ̀lú àtilẹ́yìn àwọn ara Amẹ́ríkà nípasẹ̀ àjọ United States Agency for International Development (USAID) lábẹ́ ètò The Initiative (Nọ́ḿbà Ìwé-Àdéhùn: AID-620-C-15 -00002).

Àtẹ̀jáde kìn-ín-ni, 2021

Ẹ̀tọ́ àti Ìgbàniláyè

Àwọn ọ̀rọ̀ àti àwòrán tí a lò nínú iṣẹ́ yìí wà lábẹ́ ìwé-àṣẹ kárí-ayé ti àjọ Creative Commons Attribution 4.0. Láti ṣe àyẹ̀wò ìwé-àṣẹ yìí, ṣe àbẹ̀wò sí http://creativecommons.org/licenses/by/4.0/. Lábẹ́ àṣẹ àjọ Creative Commons Attribution, ẹ ní òmìnira láti ṣe ẹ̀dà, pín káàkiri, ṣe àgbéjáde, àmúlò tàbí àyálò lára iṣẹ́ yìí níwọ̀n ìgbà tí ẹ bá ti lè gbé oríyìn fún òǹkọ̀wé tàbí ayàwòrán ìpìlẹ̀ iṣẹ́ yìí. Láti gbé oríyìn fún ìpìlẹ̀ iṣẹ́ ìwé yìí, ẹ lo àṣàyàn gbólóhùn yìí: “A ṣe àgbéjáde iṣẹ́ yìí lábẹ́ àṣẹ àjọ USAID tó jẹ́ agbátẹrù ìnáwó fún ètò-ẹ̀kọ́ The Initiative àti lábẹ́ Ìwé-Àṣẹ Kárí-Ayé ti àjọ Creative Commons Attribution 4.0”

# Àtẹ Àkóónú

**Ìdúpẹ́** .......... **vii**
**Àwọn Òǹkọ̀wé** .......... **viii**
**Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ láti ọ̀dọ̀ Àjọ NERDC** .......... **ix**
**Ìfáàrà** .......... **xi**
**Sáà 1** .......... **1**
Ọ̀sẹ̀ 1 .......... 2
Ọ̀sẹ̀ 2 .......... 16
Ọ̀sẹ̀ 3 .......... 31
Ọ̀sẹ̀ 4 .......... 37
Ọ̀sẹ̀ 5 .......... 43
Ọ̀sẹ̀ 6 .......... 44
Ọ̀sẹ̀ 7 .......... 50
Ọ̀sẹ̀ 8 .......... 56
Ọ̀sẹ̀ 9 .......... 62
Ọ̀sẹ̀ 10 .......... 68
**Sáà 2** .......... **69**
Ọ̀sẹ̀ 1 .......... 70
Ọ̀sẹ̀ 2 .......... 76
Ọ̀sẹ̀ 3 .......... 83
Ọ̀sẹ̀ 4 .......... 88
Ọ̀sẹ̀ 5 .......... 94
Ọ̀sẹ̀ 6 .......... 95
Ọ̀sẹ̀ 7 .......... 102
Ọ̀sẹ̀ 8 .......... 107
Ọ̀sẹ̀ 9 .......... 113
Ọ̀sẹ̀ 10 .......... 119
**Sáà 3** .......... **120**
Ọ̀sẹ̀ 1 .......... 121
Ọ̀sẹ̀ 2 .......... 127
Ọ̀sẹ̀ 3 .......... 133
Ọ̀sẹ̀ 4 .......... 139
Ọ̀sẹ̀ 5 .......... 145
Ọ̀sẹ̀ 6 .......... 146
Ọ̀sẹ̀ 7 .......... 152
Ọ̀sẹ̀ 8 .......... 158
Ọ̀sẹ̀ 9 .......... 164
Ọ̀sẹ̀ 10 .......... 170

# Ìdúpẹ́

Àkójọpọ̀ àwọn olùkọ́ni àti àwọn amòye ló ṣe àgbékalẹ̀ ètò ìwé-kíkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ yìí lábẹ́ ìtọ́sọ́nà àjọ Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC) àti àjọ USAID tí ó ṣe agbátẹrù ìnáwó iṣẹ́ yìí fún àjọ The Initiative. A le rí orúkọ àwọn olùkópa iṣẹ́ yìí ní oju-iwe iii. Ọ̀jọ̀gbọ́n Ismail Junaidu, Ọ̀gá-Àgbà àjọ NERDC, ṣe àtìlẹ́yìn fún ètò yìí láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ títí dé ìparí. Denise O'Toole àti Dr. Nura Ibrahim láti àjọ United States Agency for International Development (USAID) ṣe àtìlẹyìn pẹ̀lú ìtọ́sọ́nà àti ìmọ̀ràn ní gbogbo ipele àgbékalẹ̀ ètò iṣẹ́ yìí. Ọ̀mọ̀wé Nurudeen Lawal, Lydia Ezihe Onuoha, Mark Hamilton, Zahra'u Abubakar Maishanu, Zaliha Nasiruddeen Bello, Joy du Plessis, Mary Sugrue, àti Corrie Blankenbeckler lo ìmọ̀ ètò ìwé-kíkà wọn láti ṣiṣẹ́ takuntakun fún àgbéjáde iṣẹ́ yìí. Àjọ SIL International ṣe àtilẹ́yìn fún àgbékalẹ̀ kọ̀ríkúlọ̀ọ̀mù tí a nílò láti ṣe ìtọ́ni fún kíkọ àwọn ìwé kikà titun náà nípa ṣíṣe àmúlò ọgbọ́n àtinúdá ti ìmọ-ẹ̀rọ Synphony. Ọ̀mọ̀wé Nasir M. Baba ni ó ṣàbójútó iṣẹ́ náà nígbà tí Ọpẹ́yẹmí Ogúnlẹ́yẹ ṣe ìpèsè ìlò ẹ̀rọ ìkànsí-ara-ẹni fún ìpàdé ìfọ̀rọ̀wérọ̀ orí ẹ̀rọ. Àwọn tí ó ṣe ìyàwòrán gíráfíìkì inú iwé náà ni Godwin Ondoma, Samson Lawrence, Christian Ikpe, àti Aliyu Sani. John Àkànbí Nhorj, Aliyu Sani, Ernest Ibe àti Uche Idu ni àwọn aṣàpèjúwe àwòrán inú àwọn ìwé náà.

# Àwọn Òǹkọ̀wé

| Orúkọ | Adírẹ́sì tàbí Orúkọ Ilé-Iṣẹ́ |
|---|---|
| Adeleye Timilehin | National Commission for Colleges of Education, Abuja |
| Adeosun Adetayo Joseph | Olabisi Onabanjo University, Ago Iwoye |
| Adepoju Folasade Funmilayo | Jagunmolu Girls' Senior Secondary School, Bariga, Lagos |
| Adeyemi Abiodun Adeyinka | University of Ibadan |
| Adigun Fatima Dasola | National Commission for Colleges of Education, Abuja |
| Aisha Bamanga | Universal Basic Education Commission, Abuja |
| Akinwande Olaide | Foursquare International School, Asero, Abeokuta |
| Alawiye Basheer Adisa | Lagos State University, Ojo |
| Audu Rosemary Busayo | Lagos State University, Ojo |
| Bakare Olatunji Babatunde | Michael Otedola College of Primary Education, Noforija-Epe |
| Bilyaminu Bello Inuwa | Bayero University, Kano |
| Bukola R. Adeleke | Ìṣẹ̀dálẹ̀ Media concept |
| Dámiláre Samson Oyèdélé | Yorùbá di Wúrà, Lagos |
| Daniel Abiodun Oluwafemi | No. 7, Abokanle, Street, Sekona, Ede |
| Dr. (Mrs.) Iyabode Deborah Akande | Obafemi Awolowo University, Ile-Ife |
| Dr. Margaret Lawani | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |
| Dr. Mark Hamilton | The Initiative |
| Dr. Michael Olugbenga Ajileye | Alvan Ikoku Federal College of Education, Owerri |
| Dr. Oyedeji Victor Abimbola | Federal College of Education, Zaria |
| Dr. (Mrs.) Elizabeth Adebisi Banjo | University of Lagos, Akoka |
| Iyabode Baliquis Alaga | University of Ibadan |
| Lydia Ezihe Onuoha | The Initiative |
| Mary Ogbene Abah | Teachers' Registration Council of Nigeria, Abuja |
| Moses Ayọ̀bámi Oyèdélé | Yorùbá di Wúrà, Lagos |
| Mr. Aina Opeyemi | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |
| Mrs. Babalola Victoria Olubanwo | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |

| | |
|---|---|
| Mrs. Afolayan A. Funmilayo | Kwara State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Ipinlaye Omolola | Ondo State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Jumoke Fagbohun | Ekiti State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Kolade Bose O | Osun State Univeral Basic Education Board |
| Mrs. Ladipo Olaide | Oyo State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Olayinka Ogungbayi | Ogun State Universal Basic Education Board |
| Nurudeen Lawal | The Initiative |
| Ojo Olubunmi Ayobami | The Bridge College, Abeokuta |
| Olayinka Phebe Olayemi | Federal Government College, Ijaniki |
| Omotoyosi Ishola | Camilla Brook Place School, Lagos |
| Opeoluwa Taiwo | University of Ibadan |
| Patience Abiodun | Lagos State Universal Basic Education Board |
| Prof. Oluyemisi Adebowale | Adekunle Ajasin University, Akungba-Akoko |
| Professor Solomon Olanrewaju Makinde | Lagos State University, Ojó |
| Rifqat Opeyemi Sanni | Adeniran Ogunsanya College of Education, Oto/Ijanikin |
| Sakiru Kazeem Adeniyi | Adeniran Ogunsanya College of Education, Oto/Ijanikin |
| Segun Adenipekun Olanibi | Aminu Saleh College of Education, Azare |
| Sulaymon Muhammad Raji | Adeyemi College of Education, Ondo |
| Zaliha Nasiruddeen Bello | The Initiative |
| Zahra'u Abubakar Maishanu | The Initiative |
| Olatunde Bamidele Eniola | Lagos State Universal Education Board |

# Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ

Ìmọ̀ ìwé-kíka ṣe pàtàkì fún àwọn ọmọde láti lè ṣe àṣeyege ní ilé-ẹ̀kọ́ àtí ní ìyókù ìgbé-ayé wọn lẹ́yìn tí wọ́n bá parí ẹ̀kọ́ wọn. Síwájú sí i, ìlànà ìkọ́ni ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé àti ìtọ́sọ̀nà tó péye ṣe pàtàkì jọjọ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè ní ìmọ̀ tí ó yè kooro nínú ìwé-kíkà, ní pàtàkì jùlọ láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ẹ̀kọ́ wọn. Àbájáde iṣẹ́ ìwádìí ni orílẹ̀ èdè-Nàìjíríà àti ní àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn ti fi hàn kedere pé ìlànà ìkọ́ni àti ìtọ́sọ̀nà tó yè kòoro ló lè mú ìdàgbàsókè bá ìmọ̀ọ̀ṣe nínú ìwé-kíka àwọn ọmọdé láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ayé wọn. Ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ìfàsẹ́yìn púpọ̀ nínú ìmọ̀ ìwé-kíkà. Ẹ̀yí ló mú kí àwọn àgbà-ọ̀jẹ̀ nínú ètò-ẹkọ jákè-jádò àgbáyé fẹnu kò láti gùn lé àṣeyọrí ètò ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà tí àwọn ìpínlẹ̀ mélòó kan ni orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tí ń múlò. Àwọn ìgbésẹ̀ yìí ṣe pàtàkì láti lè mú ìlọsíwájú tó péye bá ètò ìkọ́ni àti ìkẹ́kọ̀ọ́ ní jáke-jádò orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Fún ìdí èyi, inú mi dùn láti ṣe àfihàn ètò tuntun tí a pè ní *Jẹ́ Ká Kàwé!* tí ó wà fún ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ (kíláàsì kìn-ín-ní títí dé ìkẹ́ta) ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní àwọn ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti ń sọ èdè Yorùbá ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

Pẹ̀lú àjọṣepọ̀ gidi láàrin ìjọba àpapọ̀ àti àwọn ìjọba ìpínlẹ̀, pẹ̀lú ìnáwó tó péye láti ọ̀dọ̀ àjọ USAID, àjọ The Initiative Project ṣe àtìlẹyìn ńlá fún àgbéjáde àwọn ìwé kọ̀ṣeémánìí yìí láti mú kí ìkọ́ni àti ìkẹ́kọ̀ọ́ ìwé-kíkà ní àwọn ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti ń sọ èdè Yorùbá ní ìhà gúúsù orílẹ̀-èdè Nàìjíríà le kún ojú òṣùwọ̀n. A dúpẹ́ gidigidi lọ́wọ́ àjọ *United States Agency for International Development (USAID)* fún ìrànlọ́wọ́ wọn èyí tí o mú kí àgbéjáde àkànṣe iṣẹ́ yìí wáyé, èyí tí ó sì fún wa ní ìdánílójú pé àṣeyọrí tó tẹ̀wọ̀n nínú ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọdé jẹ́ ohun tó ṣeéṣe.

Ètò tuntun tí a mọ̀ sí *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí wáyé ní àsìkò tí ó tọ́ tí ó sì yẹ, gbogbo ara ni a sì fi ṣe àtìlẹ́yìn fún ètò yìí. Láìṣe-àní-àní, ètò kárí-ayé ni ètò ìdàgbàsókè ìmọ̀ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọdé, orílẹ̀-èdè wa Nàìjíríà kò sì kẹ̀rẹ̀ rárá nínú àtìlẹ́yìn wa fún ètò náà. Àgbékalẹ̀ ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí tẹ̀lé àwọn ìlànà ìkẹ́kọ̀ọ́ káríayé tí ó dára jùlọ fún ìwé-kíkà, pẹ̀lú ìtọ́nisọ́nà, ọgbọ́n àti ìrírí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àgbà-ọ̀jẹ̀ onímọ̀ ìkọ́ni, onímọ̀ èdè Yorùbá, àti àwọn onímọ̀ kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù káàkiri àwọn ìpínlẹ̀ àti láti ọ̀dọ̀ ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Àgbékalẹ̀ àwọn ìwé yìí sì tún tẹ̀lé àwọn ìlànà ẹlẹ́rìí tó dájú fún ìtọ́nísọ́nà lórí ìwé-kika tí a ti lò pẹ̀lú àbájáde tó gbé ògo yọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ní àwọn orílẹ̀-èdè mîìrán káàkiri àgbáyé.

Àṣeyọrí ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ yìí wà lọ́wọ́ àwọn olùkọ́. Àwọn ni agbátẹ̀rù àkọ́kọ́ fún àṣeyọrí ètò yìí. Ìmọ̀, ìfẹ́-inú àtí agbára wọn ṣe pàtàkì fún àbájáde ètò yìí. Nítorí náà, o ṣe pàtàkì pé kí gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ ẹ̀kọ́ jẹ lógún fọwọsowọ́pọ̀ láti rí i dájú pé àwọn olùkọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ rí àtìlẹ́yìn tó péye gbà láti lè ṣe ìrànwọ́ fún àwọn ọmọ wa lórí ìmọ̀ ìwé-kíkà. Kí èyí le ṣeéṣe, àwọn olùkọ́ níláti máa ṣe ìtọ́nisọ́na àti àtìlẹ́yìn fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti mú ìwé-kíkà àti ìwé-kíkọ lóòrè-kóòrè bí iṣẹ́.

Àwọn òbí náà ní ipa pàtàkì láti kó nípa ṣíṣe kóríyá fún àwọn ọmọ wọn láti máa ṣe iṣẹ́ ìwé-kíkà àti ìwé-kíkọ láyè ara wọn nígbà gbogbo àti láti rí i pé àwọn ọmọ ń lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ lásìkò àti lójoojúmọ. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, àwọn òbi gbọ́dọ̀ rí i dájú pé àwọn ọmọ wọn ní ìfẹ́ sí ìwé-kíkà. Yàtọ̀ sí àwọn ọ̀nà ìkọ́ni tí olùkọ́ ń lò, ìfẹ́ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá ní sí ìwé-kíkà ni yóò ṣe atọ́kùn ìfẹ́ tí wọ́n máa ní sí ètò ẹ̀kọ́ ní gbogbo ọjọ́ ayé wọn, èyí tí ó sì máa ṣe okùnfà àṣeyege ní ilé-ẹ̀kọ́ àtí lẹ́yìn tí wọ́n bá parí ẹ̀kọ́ wọn.

Àwọn alákòóso ètò ẹ̀kọ́ ní gbogbo àwọn ìpínlẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá gbọ́dọ̀ rí i pe wọ́n ra ohun-èlò pàtàkì fún ìwé-kíkà yìí, kí wọ́n si rí i pé àwọn ìwé yìí dé ọwọ́ gbogbo àwọn olùkọ́, àwọn

akẹ́kọ̀ọ́ àti gbogbo ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ jáke-jádo ilẹ̀ Yoruba. Lára ojúṣe wọn sì tún ni láti rí i pé wọ́n n pèsè ètò ìdàgbàsókè-lẹ́nu-iṣẹ́ fún àwọn olùkọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ lóòrè-kóòrè. Èyí ṣe pàtàkì púpọ̀ fún àṣeyọrí ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí. Ojúṣe gbogbo wa ni lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà yìí láti rí i pé ìpìlẹ̀ ètò yìí fẹsẹ̀ múlẹ̀ dáadáa fún ìlọsíwàjú ẹ̀kọ́ àwọn ọmọ wa lóní àti lọ́jọ́ ìwájú. A tún rọ àwọn olùkọ́ lẹ́ẹ̀kan sí láti rí i pé wọ́n ń ṣe àmúlo àwọn ìwé yìí lójoojúmọ́ pẹ̀lú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn. Èyí ṣe kókó fún ìdàgbàsókè ìmọ̀ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọ wa. Tí a bá le gbé àwọn ìgbésẹ̀ pàtàkì yìí, ìdánilójú gidi wà pé ọjọ́ ọ̀lá àwọn ọmọ wa, ọjọ́ ọ̀la àwọn abúlé àti ìlú wa, ọjọ́ ọ̀la àwọn ìpínlẹ̀ wa àti ọjọ́ ọ̀la orílẹ̀-èdè wa yóò dára sí i.

**Prof. Ismail Junaidu**

Ọ̀gá Àgbà
Àjọ *Nigerian Educational Research and Development Council*

# Ìfáàrà

A ṣe àgbékalè ìwé yìí láti pesè ọgbọ́n àti ìmọ̀ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ọlọ́dún mẹ́ta àkọ́kọ́ nílò fún kíka ìwé ní àkàyé. Ẹ̀rí tí a gbà láti ínú iyàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́ ní ìhà àríwá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tí ó lè kàwé ní èdè abínibíbi kò tó nǹkan. Kódà, ìwádìí káàkiri àgbáyé fi ìdi ohun tí ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀-ìkọ́ni ti mọ̀ múlẹ̀ pé: Nígbà tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ bá lè kàwé jágaara pẹ̀lú àkàyé nínú èdè abínibí wọn, ló tó ṣe é ṣe kí irúfẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bẹ́ẹ̀ ṣe àṣeyọrí tó péye nílé-ẹ̀kọ́. Àwọn ìmọ̀ àti ọgbọ́n ìkàwé tí àwọn ọmọdé ti kọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ẹ̀kọ́ wọn yóò ran kíkọ́ ẹ̀kọ́ èdè mìíràn lọ́wọ́ bí ọmọ́ bá ṣe ń dàgbà sí i. Síwájú síi, ìmọ̀ àti ọgbọ́n ìkàwé fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ máa ń ran kíkọ́ ẹ̀kọ́ mìíràn lọ́wọ́ nínú èyí tí ìwé-kíkà pọn dandan. Láìdéènà pẹnu, bí ọmọ ṣe lè kàwé sí wà lọ́wọ́ irú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ọmọ́ náà gbà nínú yàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́.

Àṣeyọrí èto ìwé-kíkà yìí wà lọ́wọ́ ìmọ̀, òye àti ọgbọ́n àwọn olùkọ́ tó ń kọ́ àwọn ọmọ nínú iyàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́, àti ìfarajìn wọn láti jẹ́ kí àyọrisí rere bá ìwé-kíkà. Síbẹ̀, ìfarajìn tí ó lọ́ọ̀rìn nípasẹ̀ ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn òbí àti àwùjọ. Ojúṣe àwọn òbí ni láti rí i dájú pé ẹ̀kọ́ kíkọ́ wáyé, pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti àtìlẹ̀yìn àwọn mìíràn tó wà ní àwùjọ ilé-ẹ̀kọ́. Ọmọ kọ̀ọ̀kan ni a gbọ́dọ̀ fún ní ìwé láti lè mú kí ìwé-kíkà wọn gbilẹ̀ sí i. Àwọn ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ àti àwọn olùkọ́ gbọ́dọ̀ rí i dájú pé ìwé yìí wà ní àrọ́wọ́tó àwọn akẹ́kọ̀ọ́, kì í ṣe èyí tí à ń tọ́jú pamọ́ síbìkan láìlò. Ọ̀fẹ́ ni a gbọ́dọ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kí àwọn akékọ̀ọ́ lè ní ànfààní níní àti lílo àwọn ohun-èlo láti lè yege. A gbọ́dọ̀ rí i dájú pé a gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ níyànjú láti máa mú ìwe wọn lọ sí ilé. Ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, ó ṣe pàtàkì pé kí àwọn òbí náà máa ran àwọn ọmọ lọ́wọ́ lórí àwọn iṣẹ́-àṣetiléwá, kí wọ́n rí i dájú pé ó yé wọn kí wọ́n sì ṣe é bó ti tọ́ àti bó ti yẹ. Àwọn òbí gbọ́dọ̀ máa kàwé tàbí kà ìtàn sí etí igbọ́ àwọn ọmọ wọn; kí wọ́n máa tẹ́tísílẹ̀ gbọ́ ohun tí àwọn ọmọ wọn ń ká fún wọn, kí wọ́n máa sọ ìtàn fún wọn, kí wọ́n sì máa ran àwọn ọmọ wọn lọ́wọ́ nínú àkọsílẹ̀ nípa ṣíṣe iṣẹ́ yìí lójoojúmọ́. Ìgbà yìí nìkan ni àwọn ọmọ lè yege bí wọ́n ṣe ń dàgbà sí i nínú ìmọ̀ àti ọgbọ́n àti láti ní ìfẹ sí ìwé kíkà - láti kàwé àti láti kàwé náà dáadáa.

A kọ ìwé tí à ń sọ nípa rẹ̀ yìí ní ìbámu pẹ̀lú èròńgbà pé gbogbo ará, ọ̀rẹ́ àtí mọ̀lẹ́bí ọmọ ló ní ipa pàtàkì láti kó nínú ríran ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà ọmọ lọ́wọ́, pàápàá jùlọ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Àwọn olùkọ́ àti òbí ló kó ipa tó ga jùlọ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe là á kalẹ̀ níbí. Síbẹ̀, àwọn olùkọ́ àti òbí gbọ́dọ̀ mọ̀-ọ́-mọ̀ máa ṣe ohun tó máa mú kí ìkẹ́kọ̀ọ́ àwọn ọmọ gbèrú sí i. Ìwé yìí wà fún ìpìlẹ̀ tí a óò mọ lé; ó sì jẹ́ ohun-èlò tó ṣe kókó tí gbogbo ọmọdé nílò láti di olùfẹ́ ìwé-kíkà àti olúfẹ̀ ìkẹ́kọ̀ọ́ ní gbogbo ọjọ́-ayé wọn.



# Sáà 1

# Ọsẹ̀ 1 - 9







# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀1 Ẹ̀kọ́ 1













# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀1 Ẹ̀kọ́ 2

























# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 1 Ẹ̀kọ́ 3





















# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 1 Ẹ̀kọ́ 4













# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 1 Ẹ̀kọ́ 4

















# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 1 Ẹ̀kọ́ 5



# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 1 Ẹ̀kọ́ 5





























# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 2 Ẹ̀kọ́ 1

















































































# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 2 Ẹ̀kọ́ 4

















# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 2 Ẹ̀kọ́ 4











































Tata nìyí.

Ata nìyí.

Ata ta tata lára.

■ T t A a

● a ta

▲ tata ata atata

★ Ata ta tata lára

| | | | |
|---|---|---|---|
| T | T | T | |
| t | t | t | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| T | T | T | |
| t | t | t | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| T | T | T | |
| t | t | t | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |
| ta | ta | ta | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| T | T | T | |
| t | t | t | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |
| ta | ta | ta | |



Tárá ta ata.

Tárá fi ata ra ara.

Ata ta Tárá lára.

■ Tt Rr Aa

● ta ra

▲ ata ara tara

★ Tárá ta ata

| | | | |
|---|---|---|---|
| R | R | R | |
| r | r | r | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| R | R | R | |
| r | r | r | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| T | T | T | |
| t | t | t | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |
| ta | ta | ta | |
| ra | ra | ra | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| T | T | T | |
| t | t | t | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |
| ta | ta | ta | |
| ra | ra | ra | |



Tàlà ra ìwé.
Ìwé àtàtà ni Tàlà rà.

L l À à

là tà rà

ààlà àtàtà Tàlà

Tàlà ra ìwé

| | | |
|---|---|---|
| là<br>la | tà<br>ta | rà<br>ra |

L L L
l l l
À À À
à à à

L L L
l l l
À À À
à à à



| | | | |
|---|---|---|---|
| L | L | L | |
| l | l | l | |
| À | À | À | |
| à | à | à | |
| là | là | là | |
| tà | tà | tà | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| L | L | L | |
| l | l | l | |
| À | À | À | |
| à | à | à | |
| là | là | là | |
| tà | tà | tà | |



Tàlà rí rúlà àrà.

Tàlà fẹ́ràn rúlà àrà.

Tàlà ra rúlà àrà.

L l À à

là rà tà

àlà àrà tààrà

Tàlà ra rúlà àrà

| | | |
|---|---|---|
| là<br>la | tà<br>ta | rà<br>ra |

L
l
À
à

L
l
À
à

L
l
À
à
là
rà
tà

L
l
À
à
là
rà
tà

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

**Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà**

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ: ______________________

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

T A r l À R

**Ìpín 2: Sílébù**

tà ta ra là rà a

**Ìpín 3: rọ̀**

Tárá àlà tata ara tààrà ààlà

**Ìpín 4: Àyọkà**

Ata Tárá

Tárá ta ata.

Tárá fi ata ra ara.

Ata ta Tárá lára.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Ta ni ó ta ata?
2. Kí ni Tara fi ra ara?
3. Kí ni Tara lè ṣe bí ata ṣe ń ta á lára?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

à t R l

**Àríwísí Olùkọ́:**



Tàlà rí àkàlà ní oko.

Tàlà mú àkàlà.

Tàlà ta àkàlà.

K k O o

ko kà là

oko àkàrà àkàlà

Tàlà mú àkàlà

| | | |
|---|---|---|
| ko | to | lo |
| kà | tà | là |
| ka | ta | la |

| | | | |
|---|---|---|---|
| K | K | K | |
| k | k | k | |
| O | O | O | |
| o | o | o | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| K | K | K | |
| k | k | k | |
| O | O | O | |
| o | o | o | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| K | K | K | |
| k | k | k | |
| O | O | O | |
| o | o | o | |
| ko | ko | ko | |
| kà | kà | kà | |
| là | là | là | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| K | K | K | |
| k | k | k | |
| O | O | O | |
| o | o | o | |
| ko | ko | ko | |
| kà | kà | kà | |
| là | là | là | |



Bàbá ra koto.

Tàlà ka koto.

Bàbá pín koto.

■ K k O o

● tà ko to

▲ Tàlà koko koto

★ Bàbá ra koto

| | | |
|---|---|---|
| ko | ro | lo |
| kà | rà | là |
| ka | ra | la |

| | | | |
|---|---|---|---|
| K | K | K | |
| k | k | k | |
| O | O | O | |
| o | o | o | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| K | K | K | |
| k | k | k | |
| O | O | O | |
| o | o | o | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| K | K | K | |
| k | k | k | |
| O | O | O | |
| o | o | o | |
| tà | tà | tà | |
| ko | ko | ko | |
| to | to | to | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| K | K | K | |
| k | k | k | |
| O | O | O | |
| o | o | o | |
| tà | tà | tà | |
| ko | ko | ko | |
| to | to | to | |



Tárá wá sí Àwà.

Tárá wá ta àwo ní Àwà.

W w Á á

wà wo tá

Àwà àwo Tárá

Tárá wá sí Àwà

| | | |
|---|---|---|
| wá | ká | tá |
| wo | ko | to |
| wà | kà | tà |

W W W

w w w

Á Á Á

á á á

W W W

w w w

Á Á Á

á á á



| | | | |
|---|---|---|---|
| W | W | W | |
| w | w | w | |
| Á | Á | Á | |
| á | á | á | |
| wà | wà | wà | |
| wo | wo | wo | |
| tá | tá | tá | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| W | W | W | |
| w | w | w | |
| Á | Á | Á | |
| á | á | á | |
| wà | wà | wà | |
| wo | wo | wo | |
| tá | tá | tá | |



Oko Àwà ni Tàlà wà.
Tárá ń wá Tàlà.
Tàlà ń wá tata.

■ W w Á á

● wà lá wá

▲ Àwà Tàlà wákà

★ Tárá ń wá Tàlà

| | | |
|---|---|---|
| wá | tá | ká |
| wà | tà | kà |
| wo | to | ko |

| | | | |
|---|---|---|---|
| W | W | W | |
| w | w | w | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| W | W | W | |
| w | w | w | |
| A | A | A | |
| a | a | a | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| W | W | W | |
| w | w | w | |
| Á | Á | Á | |
| á | á | á | |
| wà | wà | wà | |
| là | là | là | |
| wá | wá | wá | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| W | W | W | |
| w | w | w | |
| Á | Á | Á | |
| á | á | á | |
| wà | wà | wà | |
| là | là | là | |
| wá | wá | wá | |



Tafàtafà ni Tàfá.
Tàfá ta ọfà.
Ọfà ba àkàlà.

F f Ọ ọ

fọ fà kà

Fọlá tafàtafà àkàlà

Tafàtafà ni Tàfá

| | | |
|---|---|---|
| fọ | tọ | lọ |
| fo | to | lo |
| fa | ta | la |

| | | | |
|---|---|---|---|
| F | F | F | |
| f | f | f | |
| Ọ | Ọ | Ọ | |
| ọ | ọ | ọ | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| F | F | F | |
| f | f | f | |
| Ọ | Ọ | Ọ | |
| ọ | ọ | ọ | |

F

f

Ọ

ọ

fọ

fà

kà

F

f

Ọ

ọ

fọ

fà

kà



Tàlà ra ọ̀bọ.

Akọ ọ̀bọ ni Tàlà rà.
Àlàfo wà lọ́wọ́ ọ̀bọ Tàlà.

■ F f Ọ ọ

● kọ fo wọ

▲ akọ àlàfo awọ

★ Tàlà ra ọ̀bọ

| | | |
|---|---|---|
| fọ | wọ | bọ |
| fà | wà | bà |
| fá | wá | bá |



F F F

f f f

Ọ Ọ Ọ

ọ ọ ọ



F F F

f f f

Ọ Ọ Ọ

ọ ọ ọ



| | | | |
|---|---|---|---|
| F | F | F | |
| f | f | f | |
| Ọ | Ọ | Ọ | |
| ọ | ọ | ọ | |
| kọ | kọ | kọ | |
| fọ | fọ | fọ | |
| wọ | wọ | wọ | |



| | | | |
|---|---|---|---|
| F | F | F | |
| f | f | f | |
| Ọ | Ọ | Ọ | |
| ọ | ọ | ọ | |
| kọ | kọ | kọ | |
| fọ | fọ | fọ | |
| wọ | wọ | wọ | |



Tàfá ra akọ ajá.
Ajá Tàfá fa ajere.
Ajere fọ́ àwo Tàfá.

■ Jj Ee

● je já fá

▲ ajere ajá Tàfá

★ Ajere fọ́ àwo Tàfá

| | | |
|---|---|---|
| je | fe | ke |
| Já | fá | ká |
| jọ | fọ | kọ |

J J J

j j j

E E E

e e e

J J J

j j j

E E E

e e e

# Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 9 Ẹ̀kọ́ 1 àti 2



J J J

j j j

E E E

e e e

je je je

já já já

fá fá fá



J J J

j j j

E E E

e e e

je je je

já já já

fá fá fá



Tárá fọ ajere.

Tárá rọra ṣan ajere.

Ajá Tárá wo ajere.

Ajá Tárá jùrù.

■ J j E e

● já je re

▲ ajá ajere rere

★ Tárá rọra ṣan ajere.

| | | |
|---|---|---|
| je | re | te |
| Já | rá | tá |
| jọ | rọ | tọ |

| | | | |
|---|---|---|---|
| J | J | J | |
| j | j | j | |
| E | E | E | |
| e | e | e | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| J | J | J | |
| j | j | j | |
| E | E | E | |
| e | e | e | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| J | J | J | |
| j | j | j | |
| E | E | E | |
| e | e | e | |
| já | já | já | |
| je | je | je | |
| re | re | re | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| J | J | J | |
| j | j | j | |
| E | E | E | |
| e | e | e | |
| já | já | já | |
| je | je | je | |
| re | re | re | |

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

j Á O w F ọ

**Ìpín 2: Sílébù**

Kà je to fọ wá ko

**Ìpín 3: rọ̀**

Àwà oko wákà àkàrà ajá àlàfo

**Ìpín 4: Àyọkà**

Oko Àwà ni Tàlà wà.

Tárá ń wá Tàlà.

Tàlà ń wá tata.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Níbo ni Tárá wà?
2. Kí ni Tàlà ń wá kiri?
3. Kí ló dé ti Tárá n wá Tàlà kiri?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

f O W à

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Sáà 2
# Ọsẹ̀ 1 - 9



Tàlà àti Tàfá ja ẹkẹ.
Tàfá lẹ nínú ẹkẹ.
Tàlà ra àkàrà fún Tàfá.
Ara Tàfá le.

I i Ẹ ẹ

ti rà kẹ

àti irà Ẹkẹ

Tàfá lẹ nínú ẹkẹ

| | | |
|---|---|---|
| kẹ | lẹ | te |
| kà | là | tà |
| ká | lá | tá |

| | | | |
|---|---|---|---|
| tí | tí | tí | |
| rá | rá | rá | |
| kẹ | kẹ | kẹ | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| tí | tí | tí | |
| rá | rá | rá | |
| kẹ | kẹ | kẹ | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| tí | tí | tí | |
| rá | rá | rá | |
| kẹ | kẹ | kẹ | |
| àti | àti | àti | |
| ìrà | ìrà | ìrà | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| tí | tí | tí | |
| rá | rá | rá | |
| kẹ | kẹ | kẹ | |
| àti | àti | àti | |
| ìrà | ìrà | ìrà | |



Tàlà ra ike.

Ike Tàlà là.

Tárá bá Tàlà lẹ ike.

Tàlà àti Tárá jẹ ẹja Tàlà.

| | |
|---|---|
| ■ | I i Ẹ ẹ |
| ● | ja jẹ kẹ |
| ▲ | ẹja jíjẹ kẹẹrẹ |
| ★ | Tárá bá Tàlà lẹ ike |

| | | |
|---|---|---|
| jẹ | kẹ | lẹ |
| ja | ka | la |
| jọ | kọ | lọ |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ja | ja | ja | |
| jẹ | jẹ | jẹ | |
| kẹ | kẹ | kẹ | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ja | ja | ja | |
| jẹ | jẹ | jẹ | |
| kẹ | kẹ | kẹ | |



| | | |
|---|---|---|
| ja | ja | ja |
| jẹ | jẹ | jẹ |
| kẹ | kẹ | kẹ |
| ẹja | ẹja | ẹja |
| jíjẹ | jíjẹ | jíjẹ |
| kẹẹrẹ | kẹẹrẹ | kẹẹrẹ |



| | | |
|---|---|---|
| ja | ja | ja |
| jẹ | jẹ | jẹ |
| kẹ | kẹ | kẹ |
| ẹja | ẹja | ẹja |
| jíjẹ | jíjẹ | jíjẹ |
| kẹẹrẹ | kẹẹrẹ | kẹẹrẹ |



Ara Dára kò dá.

Tára lọ wo Dára.

Dára dìde kí Tárá.

Dára àti Tárá dì mọra.

■ D d Ì ì

● dì dá rá

▲ dìde Dára Tárá

★ Ara Dára dìde kò dá.

| | | |
|---|---|---|
| dì | jì | bì |
| da | ja | ba |
| dá | já | bá |

| | | | |
|---|---|---|---|
| dì | dì | dì | |
| dá | dá | dá | |
| ra | ra | ra | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| dì | dì | dì | |
| dá | dá | dá | |
| ra | ra | ra | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| D | D | D | |
| d | d | d | |
| Ì | Ì | Ì | |
| ì | ì | ì | |
| dìde | dìde | dìde | |
| Dára | Dára | Dára | |
| Tárá | Tárá | Tárá | |


| | | | |
|---|---|---|---|
| D | D | D | |
| d | d | d | |
| Ì | Ì | Ì | |
| ì | ì | ì | |
| dìde | dìde | dìde | |
| Dára | Dára | Dára | |
| Tárá | Tárá | Tárá | |



Tàfá rí ẹyẹ ìdì.

Tàfá lọ wo Tàlà ní ìta.

Ó fi ẹyẹ ìdì han Tàlà.

Tàfá àti Tàlà fi ẹyẹ ìdì ṣeré.

■ D d Ì ì

● dì fá tà

▲ Ìdì Tàfá ìta

★ Tàfá rí ẹyẹ ìdì

| dí | wí | tí |
|---|---|---|
| di | wi | ti |
| dá | wa | ta |

| | | | |
|---|---|---|---|
| dì | dì | dì | |
| fá | fá | fá | |
| ta | ta | ta | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| dì | dì | dì | |
| fá | fá | fá | |
| ta | ta | ta | |



| | | |
|---|---|---|
| dì | dì | dì |
| fá | fá | fá |
| ta | ta | ta |
| ìdì | ìdì | ìdì |
| dára | dára | dára |
| ìta | ìta | ìta |



| | | |
|---|---|---|
| dì | dì | dì |
| fá | fá | fá |
| ta | ta | ta |
| ìdì | ìdì | ìdì |
| dára | dára | dára |
| ìta | ìta | ìta |



Iyìọ̀lá jí Tàlà.
Tàlà yára gbá àyíká.
Iyìọ̀lá yí ilé ká láti wo àyíká.
Iyìọ̀lá yin Tàlà.

■ Y y Í í

● yá yí yì

▲ yára àyíká Iyìọlá

★ Iyìọlá yin Tàlà

| | | |
|---|---|---|
| yí | tí | jí |
| yá | tá | já |
| yọ | tọ | jọ |

| | | | |
|---|---|---|---|
| yá | yá | yá | |
| yí | yí | yí | |
| yì | yì | yì | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| yá | yá | yá | |
| yí | yí | yí | |
| yì | yì | yì | |



| | | |
|---|---|---|
| yá | yá | yá |
| yí | yí | yí |
| yì | yì | yì |
| yára | yára | yára |
| àyíká | àyíká | àyíká |
| Iyìọlá | Iyìọlá | Iyìọlá |



| | | |
|---|---|---|
| yá | yá | yá |
| yí | yí | yí |
| yì | yì | yì |
| yára | yára | yára |
| àyíká | àyíká | àyíká |
| Iyìọlá | Iyìọlá | Iyìọlá |



Iyìọ̀lá wo etí Dárà.
Iyìọ̀lá kò rí ìdọ̀tí níbẹ̀.
Iyìọ̀lá yin Dárà.

■ Y y Í í

● yì yí tí

▲ Iyìọlá àyíká etí

★ Iyìọlá yin Dárà

| | | |
|---|---|---|
| yí | dí | tí |
| yá | dá | tá |
| yà | dà | tà |

| | | | |
|---|---|---|---|
| yì | yì | yì | |
| yí | yí | yí | |
| tí | tí | tí | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| yì | yì | yì | |
| yí | yí | yí | |
| tí | tí | tí | |



| | | |
|---|---|---|
| yì | yì | yì |
| yí | yí | yí |
| tí | tí | tí |
| Iyìọlá | Iyìọlá | Iyìọlá |
| àyíká | àyíká | àyíká |
| etí | etí | etí |



| | | |
|---|---|---|
| yì | yì | yì |
| yí | yí | yí |
| tí | tí | tí |
| Iyìọlá | Iyìọlá | Iyìọlá |
| àyíká | àyíká | àyíká |
| etí | etí | etí |



Bàbá ra bọ̀ọ̀lì.
Bọ̀ọ̀lì bàbá jábọ́.
Bàbá da bọ̀ọ̀lì náà nù.
Bàbá kì í ṣọ̀bùn.

| | |
|---|---|
| ■ | B b Ọ̀ ọ̀ |
| ● | bọ̀ bà bọ |
| ▲ | bọ̀ọ̀lì bàbá ọ̀bọ |
| ★ | Bọ̀ọ̀lì bàbá jábọ́ |

| | | |
|---|---|---|
| bọ̀ | yọ̀ | dọ̀ |
| bà | yà | dà |
| bá | yá | dá |

| | | | |
|---|---|---|---|
| bọ̀ | bọ̀ | bọ̀ | |
| bà | bà | bà | |
| bọ | bọ | bọ | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| bọ̀ | bọ̀ | bọ̀ | |
| bà | bà | bà | |
| bọ | bọ | bọ | |



| | | |
|---|---|---|
| bọ̀ | bọ̀ | bọ̀ |
| bà | bà | bà |
| bọ | bọ | bọ |
| bọ̀ọ̀lì | bọ̀ọ̀lì | bọ̀ọ̀lì |
| bàbá | bàbá | bàbá |
| Ọ̀bọ | Ọ̀bọ | Ọ̀bọ |



| | | |
|---|---|---|
| bọ̀ | bọ̀ | bọ̀ |
| bà | bà | bà |
| bọ | bọ | bọ |
| bọ̀ọ̀lì | bọ̀ọ̀lì | bọ̀ọ̀lì |
| bàbá | bàbá | bàbá |
| Ọ̀bọ | Ọ̀bọ | Ọ̀bọ |




Tàlà fọ ọkọ̀ bàbá.
Ọkọ̀ bàbá mọ́.
Tàlà wọ ọkọ̀ bàbá.
Ọkọ̀ bàbá ṣí.

| | |
|---|---|
| ■ | B b Ọ̀ ọ̀ |
| ● | kọ̀ bá wọ |
| ▲ | ọkọ̀ bàbá bọ̀wọ̀ |
| ★ | Ọkọ̀ bàbá mọ́ |

| | | |
|---|---|---|
| bọ̀ | kọ̀ | wọ̀ |
| bí | kí | wí |
| bà | kà | wà |

| | | | |
|---|---|---|---|
| kọ̀ | kọ̀ | kọ̀ | |
| bá | bá | bá | |
| wọ | wọ | wọ | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| kọ̀ | kọ̀ | kọ̀ | |
| bá | bá | bá | |
| wọ | wọ | wọ | |

| | | |
|---|---|---|
| kọ̀ | kọ̀ | kọ̀ |
| bá | bá | bá |
| wọ | wọ | wọ |
| ọkọ̀ | ọkọ̀ | ọkọ̀ |
| bàbá | bàbá | bàbá |
| bọ̀wọ̀ | bọ̀wọ̀ | bọ̀wọ̀ |

| | | |
|---|---|---|
| kọ̀ | kọ̀ | kọ̀ |
| bá | bá | bá |
| wọ | wọ | wọ |
| ọkọ̀ | ọkọ̀ | ọkọ̀ |
| bàbá | bàbá | bàbá |
| bọ̀wọ̀ | bọ̀wọ̀ | bọ̀wọ̀ |

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ: ______________________

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

é p u Ò gb Ṣ

**Ìpín 2: Sílébù**

há gò ṣó pú wó gbú

**Ìpín 3: rọ̀**

gbàgbọ́ ẹyẹ ìṣó ìgò ahéré àsè

**Ìpín 4: Àyọkà**

Tàlà àti Tárá jí láàárọ̀.
Tàlà àti Tárá kí ìyá àti bàbá wọn.
Tàlà àti Tárá bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ilé.
Tàlà àti Tárá fọ aṣọ.
Bàbá fi owó ṣapala àti ṣàkì sílẹ̀.
Ìyá se ọbẹ̀ ṣàkì.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Kí ni Tàlà àti Tárá kọ́kọ́ ṣe nígbà tí wọ́n jí?
2. Kí ni ìdí tí bàbá fi fi owó sílẹ̀?
3. Kí ni ìdí tí ìyá fi se ọbẹ̀ ṣàkì?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

Dára, ipò, àsè, gogoro

**Àríwísí Olùkọ́:**



Tárá sáré-ìje.
Ó bọ́ bàtà àti ìbọsẹ̀ rẹ̀ sílẹ̀.
Ẹsẹ̀ ni Tárá fi sáré.
Ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ ní Tárá sáré-ìje.

■ S s Ẹ̀ ẹ̀

● sẹ̀ sọ̀ bọ̀

▲ ẹsẹ̀ ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ ìbọ̀sẹ̀

★ Tárá sáré-ìje

| | | |
|---|---|---|
| sẹ̀ | bẹ̀ | jẹ̀ |
| sọ̀ | bọ̀ | jọ̀ |
| sa | ba | ja |

| | | | |
|---|---|---|---|
| sẹ̀ | sẹ̀ | sẹ̀ | |
| sọ̀ | sọ̀ | sọ̀ | |
| bọ̀ | bọ̀ | bọ̀ | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| sẹ̀ | sẹ̀ | sẹ̀ | |
| sọ̀ | sọ̀ | sọ̀ | |
| bọ̀ | bọ̀ | bọ̀ | |

| | | |
|---|---|---|
| sẹ̀ | sẹ̀ | sẹ̀ |
| sọ̀ | sọ̀ | sọ̀ |
| bọ̀ | bọ̀ | bọ̀ |
| ẹsẹ̀ | ẹsẹ̀ | ẹsẹ̀ |
| ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ | ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ | ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ |
| ìbọ̀sẹ̀ | ìbọ̀sẹ̀ | ìbọ̀sẹ̀ |

| | | |
|---|---|---|
| sẹ̀ | sẹ̀ | sẹ̀ |
| sọ̀ | sọ̀ | sọ̀ |
| bọ̀ | bọ̀ | bọ̀ |
| ẹsẹ̀ | ẹsẹ̀ | ẹsẹ̀ |
| ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ | ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ | ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ |
| ìbọ̀sẹ̀ | ìbọ̀sẹ̀ | ìbọ̀sẹ̀ |



Tàlà ṣeré àkàbà.

Tàlà sọ̀kalẹ̀ láti orí àkàbà.

Ẹ̀sọ̀ ni Tàlà fi sọ̀kalẹ̀ láti orí àkàbà.

S s Ẹ̀ ẹ̀

sọ̀ lẹ̀ kà

ẹ̀sọ̀ Sọ̀kalẹ̀ àkàbà

Tàlà ṣeré àkàba

| | | |
|---|---|---|
| sẹ̀ | fẹ̀ | lẹ̀ |
| sọ | fọ | lọ |
| se | fe | le |

| | | | |
|---|---|---|---|
| sọ̀ | sọ̀ | sọ̀ | |
| lẹ̀ | lẹ̀ | lẹ̀ | |
| ka | ka | ka | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| sọ̀ | sọ̀ | sọ̀ | |
| lẹ̀ | lẹ̀ | lẹ̀ | |
| ka | ka | ka | |



| | | |
|---|---|---|
| sọ̀ | sọ̀ | sọ̀ |
| lẹ̀ | lẹ̀ | lẹ̀ |
| kà | kà | kà |
| sọ̀kalẹ̀ | sọ̀kalẹ̀ | sọ̀kalẹ̀ |
| ẹ̀sọ̀ | ẹ̀sọ̀ | ẹ̀sọ̀ |
| àkàbà | àkàbà | àkàbà |



| | | |
|---|---|---|
| sọ̀ | sọ̀ | sọ̀ |
| lẹ̀ | lẹ̀ | lẹ̀ |
| kà | kà | kà |
| sọ̀kalẹ̀ | sọ̀kalẹ̀ | sọ̀kalẹ̀ |
| ẹ̀sọ̀ | ẹ̀sọ̀ | ẹ̀sọ̀ |
| àkàbà | àkàbà | àkàbà |



Tàlà yege níbi ìdíje igi fífò.
A fi àmì ẹ̀yẹ dá a lọ́lá.
Màmá ra omele fún un.

# Mm Ee

## me mì má

## omele àmì màmá

## A fi àmì ẹ̀yẹ dá a lọ́lá

| | | |
|---|---|---|
| me | ge | ye |
| mi | gị | yị |
| mẹ̀ | gẹ̀ | yẹ̀ |

| | | | |
|---|---|---|---|
| me | me | me | |
| mì | mì | mì | |
| mà | mà | mà | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| me | me | me | |
| mì | mì | mì | |
| mà | mà | mà | |

| | | |
|---|---|---|
| me | me | me |
| mì | mì | mì |
| mà | mà | mà |
| omele | omele | omele |
| àmì | àmì | àmì |
| màmá | màmá | màmá |

| | | |
|---|---|---|
| me | me | me |
| mì | mì | mì |
| mà | mà | mà |
| omele | omele | omele |
| àmì | àmì | àmì |
| màmá | màmá | màmá |



Àwọn eléré wọ aṣọ mèremère.
Níbi ìdíje eré sísá.
Tárá sáré lemọ́lemọ́ bí ehoro.
Ó gba àmì àti ife ẹ̀yẹ.

■ M m E e

● ré mè mọ́

▲ Eléré mèremère lemọ́lemọ́

★ Ó gba àmì àti ife ẹ̀yẹ

| | | |
|---|---|---|
| me | re | le |
| mọ | rọ | lọ |
| mé | ré | lé |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ré | ré | ré | |
| mè | mè | mè | |
| mọ | mọ | mọ | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ré | ré | ré | |
| mè | mè | mè | |
| mọ | mọ | mọ | |



| | | |
|---|---|---|
| ré | ré | ré |
| mè | mè | mè |
| mọ | mọ | mọ |
| eléré | eléré | eléré |
| mèremère | mèremère | mèremère |
| lemọ́lemọ́ | lemọ́lemọ́ | lemọ́lemọ́ |



| | | |
|---|---|---|
| ré | ré | ré |
| mè | mè | mè |
| mọ | mọ | mọ |
| eléré | eléré | eléré |
| mèremère | mèremère | mèremère |
| lemọ́lemọ́ | lemọ́lemọ́ | lemọ́lemọ́ |



Ìyá Tárá ń ta ìrẹsì.

Ó ní ìsọ̀ ṣókóló àti kóló.

Ó ń ta ẹja àti ẹ̀wà náà.

Ó kó owó sí kóló.

## Sáà 2 Ọ̀sẹ̀ 8 Ẹ̀kọ́ 1 àti 2

# Ṣ ṣ Ó ó

ṣó ló wó

ṣókóló kóló owó

Ó ní ìsọ̀ ṣókóló àti kóló

| | | |
|---|---|---|
| ṣó | kó | ló |
| ṣí | kí | lí |
| ṣé | ké | lé |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ṣó | ṣó | ṣó | |
| ló | ló | ló | |
| wó | wó | wó | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ṣó | ṣó | ṣó | |
| ló | ló | ló | |
| wó | wó | wó | |

| | | |
|---|---|---|
| ṣó | ṣó | ṣó |
| ló | ló | ló |
| wó | wó | wó |
| ṣókóló | ṣókóló | ṣókóló |
| kóló | kóló | kóló |
| owó | owó | owó |

| | | |
|---|---|---|
| ṣó | ṣó | ṣó |
| ló | ló | ló |
| wó | wó | wó |
| ṣókóló | ṣókóló | ṣókóló |
| kóló | kóló | kóló |
| owó | owó | owó |




Bàbá lọ sí Ṣókótó.

Bàbá ra pákó àti ìṣó.

Bàbá ta ìṣó ní Owódé.

Bàbá di olówó.

| | |
|---|---|
| ■ | Ṣ ṣ Ó ó |
| ● | ló ṣó kó |
| ▲ | Olówo Ṣókótó ìṣó |
| ★ | Bàba ra pákó àti ìṣó. |

| | | |
|---|---|---|
| ṣó | tó | wó |
| ṣọ | tọ | wọ |
| ṣi | ti | wi |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ló | ló | ló | |
| ṣó | ṣó | ṣó | |
| kó | kó | kó | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ló | ló | ló | |
| ṣó | ṣó | ṣó | |
| kó | kó | kó | |



| | | |
|---|---|---|
| lọ́ | lọ́ | lọ́ |
| ṣọ́ | ṣọ́ | ṣọ́ |
| kọ́ | kọ́ | kọ́ |
| olọ́wo | olọ́wo | olọ́wo |
| ṣọ́kọ́tọ́ | ṣọ́kọ́tọ́ | ṣọ́kọ́tọ́ |
| ìṣọ́ | ìṣọ́ | ìṣọ́ |



| | | |
|---|---|---|
| lọ́ | lọ́ | lọ́ |
| ṣọ́ | ṣọ́ | ṣọ́ |
| kọ́ | kọ́ | kọ́ |
| olọ́wo | olọ́wo | olọ́wo |
| ṣọ́kọ́tọ́ | ṣọ́kọ́tọ́ | ṣọ́kọ́tọ́ |
| ìṣọ́ | ìṣọ́ | ìṣọ́ |



Onișòwò ni Tàfá.
Tàfá rí owó lórí pátákó kan.
Tàfa dá owó naa padà fún ọ̀gá.
Ọ̀gá fún Tàfá ní ipò.

■ P p Ò ò

● pó pa tá

▲ Òpópónà padà pátákó

★ Ọ̀gá fún Tàfá ní ipò

| | | |
|---|---|---|
| pò | tò | wò |
| pó | tó | wó |
| pa | ta | wa |

| | | | |
|---|---|---|---|
| pò | pò | pò | |
| pó | pó | pó | |
| pa | pa | pa | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| pò | pò | pò | |
| pó | pó | pó | |
| pa | pa | pa | |

| | | |
|---|---|---|
| pó | pó | pó |
| pá | pá | pá |
| tá | tá | tá |
| òpópónà | òpópónà | òpópónà |
| padà | padà | padà |
| pátákó | pátákó | pátákó |

| | | |
|---|---|---|
| pó | pó | pó |
| pá | pá | pá |
| tá | tá | tá |
| òpópónà | òpópónà | òpópónà |
| padà | padà | padà |
| pátákó | pátákó | pátákó |



Iṣẹ́ Oníròyìn ni Bàbá Tárá ń ṣe.
Ó ń ṣiṣẹ́ ní òpópónà Owódé.
Bàbá Tárá ń polówó ọjà pẹ̀lú.
Ẹni pàtàkì ni Bàbá Tárá.

■ P p Ò ò

● pò po pa

▲ pòórá polówó pàtàkì

★ Bàbá Tárá ń polówó ọjà pẹ̀lú

| | | |
|---|---|---|
| pò | tò | sò |
| pí | tí | sí |
| pà | tà | sà |

| | | | |
|---|---|---|---|
| pò | pò | pò | |
| po | po | po | |
| pa | pa | pa | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| pò | pò | pò | |
| po | po | po | |
| pa | pa | pa | |



| | | |
|---|---|---|
| pò | pò | pò |
| po | po | po |
| pa | pa | pa |
| pòórá | pòórá | pòórá |
| polówó | polówó | polówó |
| pàtàkì | pàtàkì | pàtàkì |



| | | |
|---|---|---|
| pò | pò | pò |
| po | po | po |
| pa | pa | pa |
| pòórá | pòórá | pòórá |
| polówó | polówó | polówó |
| pàtàkì | pàtàkì | pàtàkì |

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

**Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà**

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

m an ÌN n UN ọn

**Ìpín 2: Sílébù**

kùn gbọn yìn run ṣin

**Ìpín 3: rọ̀**

òkun Ọdẹ́rìndé Gbénga òfin ẹkùn ràkúnmí

**Ìpín 4: Àyọkà**

Tàfá ní aṣọ ìṣeré mẹ́rin.
Dára láṣọ ìṣeré kan.
Àwọn méjèèjì ni aṣọ eré bọ́ọ̀lù.
Tàfá ni bàtà ìgbábọ́ọ̀lù kan.
Dára fún Tàfá ní bàtà ìgbábọ́ọ̀lù kan.
Tàfá náà fún Dára láṣọ ìṣeré kan.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Aṣọ eré mélòó ni Tàfá ní?
2. Dárúkọ ohun èlò méjì tí à ń lò fún eré bọ́ọ̀lù?
3. Kí ni Dára fún Tàfá?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

ìrìn fanda ẹ̀fọn ikún

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Sáà 3

# Ọ̀sẹ̀ 1 - 9



Àná ni ọjà Owódé.

Ìyá Tárá lọ sí ọjà.

O ṣe gudugudu ní Ọjà.

Ó san owó iṣu tí ìyáàgbà rà.

Ìyá Tárá nàà ra iṣu ni ọjà.

Ó ra ẹ̀wà fún èkuru.

G g U u

ga gu ge

gudugudu garawa èkuru iṣu

Ó ra ẹ̀wà fún èkuru.

| | | |
|---|---|---|
| gu | yu | ku |
| ge | ye | ke |
| ga | ya | ka |

| | | |
|---|---|---|
| gudugudu | gudugudu | gudugudu |
| garawa | garawa | garawa |
| ekuru | ekuru | ekuru |
| iṣu | iṣu | iṣu |

| | | |
|---|---|---|
| gudugudu | gudugudu | gudugudu |
| garawa | garawa | garawa |
| ekuru | ekuru | ekuru |
| iṣu | iṣu | iṣu |



Àná ni ọjà owódé



Ó san owó iṣu tí

Ìyáàgbà rà



Tàfá lọ wo Tàlà nílé.

Ó bá ìyà Tàlà náà nílé.

Iyá sọ ìtàn gudugbẹ̀ tó bẹ́ lọ́jà.

Bàbá náà dá si.

Bàbá ròyìn gudugudu ti ìyálọ́jà ṣe.

■ G g U u

● gu tà lọ́

▲ gudugbẹ̀ gudugudu Tàfá lọ́jà

★ Iyá sọ ìtàn gudugbẹ̀ tó bẹ́ lọ́jà.

| gu | du | lu |
|---|---|---|
| gá | dá | lá |
| gọ | dọ | lọ |



| | | |
|---|---|---|
| gudugbẹ̀ | gudugbẹ̀ | gudugbẹ̀ |
| gudugudu | gudugudu | gudugudu |
| Tàfá | Tàfá | Tàfá |
| lọ́jà | lọ́jà | lọ́jà |



| | | |
|---|---|---|
| gudugbẹ̀ | gudugbẹ̀ | gudugbẹ̀ |
| gudugudu | gudugudu | gudugudu |
| Tàfá | Tàfá | Tàfá |
| lọ́jà | lọ́jà | lọ́jà |



ó bá ìyà Tàlà nílé.



Tàfá lọ wo Tàlà nílé.



Àgbẹ̀ ni Gbádé.

Gbádé gbin gbúre àti ìgbá.

Gbúre àti ìgbá Gbádé gbó.

Inú Gbádé dùn.

| | |
|---|---|
| ■ | GB gb Ú ú |
| ● | gbú gbá gbó |
| ▲ | Gbúre ìgbá gbó Gbádé |
| ★ | Inú Gbádé dùn |

| | | |
|---|---|---|
| gbú | rú | dú |
| gbi | ri | di |
| gbá | rá | dá |

| | | |
|---|---|---|
| gbúre | gbúre | gbúre |
| ìgbá | ìgbá | ìgbá |
| gbó | gbó | gbó |
| Gbádé | Gbádé | Gbádé |

| | | |
|---|---|---|
| gbúre | gbúre | gbúre |
| ìgbá | ìgbá | ìgbá |
| gbó | gbó | gbó |
| Gbádé | Gbádé | Gbádé |



Àgbẹ ni Gbádé.

Àgbẹ́ ni Gbádé.



inú Gbádé dún

inú Gbádé dún



Àgbẹ̀ ni Gbádé ní Awà.
Gbádé ń ká èso ìgbá lóko.
Ó gbúròó Tàlà tó ń bọ̀.
Tàlà bá a kó èso ìgbá.
Ìyàwó Gbádé fi èso ìgbá ṣe irú.

GB gb Ú ú

gbú gbá rú

gbúròó Gbádé irú

Gbádé ń ká èso ìgbá lóko.

| | | |
|---|---|---|
| gbú | rú | bú |
| gbá | rá | bá |
| gbọ̀ | rọ̀ | bọ̀ |

gbúròó

Gbádé

irú

igbá

gbúròó

Gbádé

irú

igbá

Àgbẹ̀ ni Gbádé ni Àwà.

Àgbẹ̀ ni Gbádé ni Àwà.

ó gbúròó Tàlà tó ń bọ̀.

ó gbúròó Tàlà tó ń bọ̀.



Abúlé Àwà ń ṣọdún ìjẹṣu.

Bàbá lọ hú iṣu lóko.

Bàbá kó iṣu sínú ahéré.

Ìyá se iṣu nínú ìkòkò.

Iṣu tí ìyá sè hooru.

# ■ H h È è

● hé lé ho hú

▲ ahére abúlé hooru húrúhúrú

★ Ìyá se iṣu nínú ìkòkò.

| | | |
|---|---|---|
| hè | sè | ṣè |
| hú | sú | ṣú |
| hí | sí | ṣí |

| | | |
|---|---|---|
| ahéré | ahéré | ahéré |
| abúlé | abúlé | abúlé |
| hooru | hooru | hooru |
| húrúhúrú | húrúhúrú | húrúhúrú |

| | | |
|---|---|---|
| ahéré | ahéré | ahéré |
| abúlé | abúlé | abúlé |
| hooru | hooru | hooru |
| húrúhúrú | húrúhúrú | húrúhúrú |

Bàbá lọ hú iṣu lóko.

Bàbá lọ hú iṣu lóko.

Bàbá kó iṣu sínú ahéré.

Bàbá kó iṣu sínú ahéré.



Eégún Aláré wà ní ìta bàbá.
Àwọn èwe ló ń ṣe ọdún.
Kò sí hílàhílo rárá.
Àwọn èèyàn ń jó.
Gbogbo èwe ń hó yèè.

■ H h È è

● è ré ha hí

▲ èwe Aláré hílàhílo háhá

★ Gbogbo èwe ń hó yèè.

| | | |
|---|---|---|
| hè | yè | lè |
| hí | yí | lí |
| ho | yo | lo |

| | | |
|---|---|---|
| ewé | ewé | ewé |
| Aláré | Aláré | Aláré |
| háhá | háhá | háhá |
| hílàhílo | hílàhílo | hílàhílo |

| | | |
|---|---|---|
| ewé | ewé | ewé |
| Aláré | Aláré | Aláré |
| háhá | háhá | háhá |
| hílàhílo | hílàhílo | hílàhílo |



ko sí hílàhílo rárá.

ko sí hílàhílo rárá.



Gbogbo èwe ní hó yètè.

Gbogbo èwe ní hó yètè.



Tárá ń lu ìlù níbi ọdún Òṣùpá.
Tárá ń fi ìlù tu àwọn ará ìlú lára.
Àwọn ará ìlú gbé òṣùbà fún un.
Dára bá Tárá nu ojú rẹ̀ nù.

■ N n Ù ù

● nù ní ṣù

▲ níùnù nínù oṣùbà òṣùpá

★ Tárá ń lu ìlù níbi ọdún Òṣùpá.

| | | |
|---|---|---|
| nù | ṣù | lù |
| ní | ṣí | lí |
| ná | ṣá | lá |

| | | |
|---|---|---|
| níùnù | níùnù | níùnù |
| nínù | nínù | nínù |
| òṣùbà | òṣùbà | òṣùbà |
| òṣùpá | òṣùpá | òṣùpá |

| | | |
|---|---|---|
| níùnù | níùnù | níùnù |
| nínù | nínù | nínù |
| òṣùbà | òṣùbà | òṣùbà |
| òṣùpá | òṣùpá | òṣùpá |

Dára bá Tóró nu gú rẹ̀ nù

Dára bá Tóró nu gú rẹ̀ nù

Tóró ńlù ìlù ńbi ọdún òṣùpá.

Tóró ńlù ìlù ńbi ọdún òṣùpá.



Bàbá náwó láti ra àgbò ọdún Ifá.

Àwọn bàbá àgbà péjọ.

Gbádé nu òpẹ̀lẹ̀ nù.

Bàbá àgbà dífá.

Ifá fọre inú wọ́n dùn.

Ijó àti ìlù sọ níbi ọdún Ifá.

■ N n Ù ù

● nù ná ní jù

▲ nùjù náwó nasẹ̀ níbi

★ Ifá fọre inú wọ́n dùn.

| | | |
|---|---|---|
| nú | jú | dú |
| ná | já | dá |
| ní | jí | dí |

| | | |
|---|---|---|
| nùjù | nùjù | nùjù |
| náwó | náwó | náwó |
| nasẹ̀ | nasẹ̀ | nasẹ̀ |
| níbi | níbi | níbi |

| | | |
|---|---|---|
| nùjù | nùjù | nùjù |
| náwó | náwó | náwó |
| nasẹ̀ | nasẹ̀ | nasẹ̀ |
| níbi | níbi | níbi |

Gbade nu ọpẹ̀lẹ̀ nu.

Gbade nu ọpẹ̀lẹ̀ nu.

Ijó àti ìlù sọ mbí ọdún fẹ́d.

Ijó àti ìlù sọ mbí ọdún fẹ́d.

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

N GB Ù H È ú

**Ìpín 2: Sílébù**

gbú hé lé nù ṣù gu

**Ìpín 3: rọ̀**

húrúhúrú gudugudu nùnu Gbúre náwó ahéré

**Ìpín 4: Àyọkà**

Eégún Aláré wà ní ìta bàbá.
Àwọn èwe ló ń ṣe ọdún.
Ko sí hílàhílo rárá.
Àwọn èèyàn ń jó.
Gbogbo èwe ń hó yèè.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Kí ni ó wà ní ìta bàbá?
2. Àwọn wo ló ń ṣe ọdún?
3. Kí ló dé tí àwọn èèyàn fi ń jó?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

oṣùbà ahègbín Gbádé èkuru

**Àríwísí Olùkọ́:**



Iyìọlá ń ta oríṣiríṣi nǹkan lórí àtẹ.
Tárá lọ ra ọjà lọ́wọ́ rẹ̀ lọ́jọ́ Ajé.
Ó ra okinni mẹ́rin àti oyin.
Ọgórin náírà ni àpapọ̀ owó rẹ̀ jẹ́.

■ IN in UN un

● rin kin yin

▲ mérin okinni oyin ìlàrin

★ Tárá lọ ra ọjà lọ́wọ́ rẹ̀ lọ́jọ́ Ajé.

| rin | kin | yin |
|---|---|---|
| run | kun | yun |

| | | |
|---|---|---|
| mẹ́rin | mẹ́rin | mẹ́rin |
| okinni | okinni | okinni |
| oyin | oyin | oyin |
| ìlàrin | ìlàrin | ìlàrin |

| | | |
|---|---|---|
| mẹ́rin | mẹ́rin | mẹ́rin |
| okinni | okinni | okinni |
| oyin | oyin | oyin |
| ìlàrin | ìlàrin | ìlàrin |

Tárá lọ ra ajá lọ́wọ́ ré lọ́jọ́ Ajé.

Inú ìgò onígun mẹ́rin ló ra oyin sí.



Irun orí bàbá ti funfun.
Ọjọ́ Àìkú ni bàbá máa n fá irun rẹ̀.
Inú àpótí onígun ni abẹ bàbá wà.
Bàbá máa ń tọ́jú abẹ ìfárí rẹ̀.

■ IN in UN un

● run gun sun fun

▲ igun funfun oorun irun

★ Irun orí bàbá ti funfun.

| gun | run | fun |
|---|---|---|
| gin | rin | fin |

| | | |
|---|---|---|
| Run | Run | Run |
| gun | gun | gun |
| sun | sun | sun |
| fun | fun | fun |

| | | |
|---|---|---|
| Run | Run | Run |
| gun | gun | gun |
| sun | sun | sun |
| fun | fun | fun |



Irun orí bàbá ti funfun.



Bàba máa ń tọ́ju abẹ
yárí rẹ̀ dára dára.



Ọmọ ogún ọdún ni Gbadé.
Gbadé tẹ̀lé bàbá lọ oko lọ́jọ́ Ẹtì.
Oko bàbá tó ìwọ̀n ibùsọ̀ méje.
Gbadé mú ikún àti yangan bọ̀.
Ẹranko kékeré ni ikún.

■ ÚN ún AN an

● gún dún kún gan

▲ ogún ọdún ikún yangan

★ Ẹranko kékeré ni ikún.

| gún | dún | kún |
|---|---|---|
| gan | dan | kan |

| | | |
|---|---|---|
| ogún | ogún | ogún |
| odún | odún | odún |
| ikún | ikún | ikún |
| yangan | yangan | yangan |

| | | |
|---|---|---|
| ogún | ogún | ogún |
| odún | odún | odún |
| ikún | ikún | ikún |
| | | |



Ẹranko kékeré ni ikún.

Ẹranko kékeré ni ikún.



Ọmọ ọgún ọdún ni Gbade.

Ọmọ ọgún ọdún ni Gbade.




Ọjọ́ Àìkú ni ìyá Tárá yan yangan.
Ọjà Owódé ni ó ti máa ń tá á.
Ìyá ní agolo kan tó fi ń ṣe òdíwọ̀n.

■ ÚN un AN an

● gan go wó yan

▲ yangan agolo Owódé ayanran

★ Ọjà Owódé ni ó ti máa ń tá á.

| fún | yún | gún |
|---|---|---|
| fan | yan | gan |

| | | |
|---|---|---|
| ìkan | ìkan | ìkan |
| yan | yan | yan |
| yangan | yangan | yangan |
| fúnrúgbìn | fúnrúgbìn | fúnrúgbìn |

| | | |
|---|---|---|
| ìkan | ìkan | ìkan |
| yan | yan | yan |
| yangan | yangan | yangan |
| fúnrúgbìn | fúnrúgbìn | fúnrúgbìn |

gà owódé ni ó ti máa
ń tà á.

Ìyá ní agolo kan tó ti ń
ṣe òdíwòn.



Iyìọ̣lá dé láti ìrìnajo.

Iyìọ̣lá ra kọ̀ǹpútà àgbélétan bọ̀.
Ìròyìn àgbáyé ló mú ún rà á.

Tọ̀sán tòru ló ń tan kọ̀ǹpútà rẹ̀
Àìsùn dá àìsàn ọ̀fìnkìn sí i lárá.

■ ỌN ọn ÌN ìn

● rìn fìn yìn

▲ Ìrìnàjò Ọ̀fìnkìn Ìròyìn

★ Iyìọlá ra kọ̀ǹpútà àgbélétan bọ̀.

| yìn | fìn | kìn |
|---|---|---|
| yọn | fọn | kọn |

| | | |
|---|---|---|
| Ìrìnàjò | Ìrìnàjò | Ìrìnàjò |
| Ọ̀fìnkìn | Ọ̀fìnkìn | Ọ̀fìnkìn |
| Ìròyìn | Ìròyìn | Ìròyìn |
| | | |

| | | |
|---|---|---|
| Ìrìnàjò | Ìrìnàjò | Ìrìnàjò |
| Ọ̀fìnkìn | Ọ̀fìnkìn | Ọ̀fìnkìn |
| Ìròyìn | Ìròyìn | Ìròyìn |
| | | |

Iyiolá dé láti Ìrìngò.

Iyiolá dé láti Ìrìngò.

Àìsun dá àìsàn ọ̀fìnkìn sí i lára.



Ìyáàgbà ń ṣàárò àwọn ọmọ rẹ̀.
Ìyáàgbà fi àgbọn ránṣẹ́ sí wọn.
Bàbá pe ìyáàgbà lórí fóònù
Ìyààgbà rọ bàbá kó yẹra.
Kó sì máa fọn rere ìrẹ́pọ̀.

■ ỌN ọn ÌN ìn

● gbọn fọn wọn sọn

▲ àgbọn fọnrere àwọn ẹ̀san

★ Kó sì máa fọn rere ìrẹ́pọ̀.

| | | |
|---|---|---|
| fọn | wọn | sọn |
| bọn | gbọn | rọn |

| | | |
|---|---|---|
| àgbọn | àgbọn | àgbọn |
| fọnrere | fọnrere | fọnrere |
| àwọn | àwọn | àwọn |
| ẹ̀san | ẹ̀san | ẹ̀san |

| | | |
|---|---|---|
| àgbọn | àgbọn | àgbọn |
| fọnrere | fọnrere | fọnrere |
| àwọn | àwọn | àwọn |
| ẹ̀san | ẹ̀san | ẹ̀san |

Kó sì máa fún rere
répọ̀.

Ìyáàgbà fi àgbon ránṣẹ́
sí wọn.



Tàlà nìkan ni ọmọkùnrin bàbá.
Bàbá fẹ́ràn Tárá ọmọ rẹ̀ kejì bí ojú.

Bàbá ra kọ̀ǹpútà ọmọdé fún Tárá.
Ó ra ẹrọ̀-alágbèéká fún Tàlà.
Tàlà àti Tárá rẹ́rìn-ín.
Wọ́n dúpẹ lọ́wọ́ bàbá.

■ ÙN ùn ÍN ín

● kùn bùn rín

▲ ọkùnrin ẹ̀bùn ẹ̀rín

★ Tàlà àti Tárá rẹ́rìn-ín.

| | | |
|---|---|---|
| kùn | bùn | rùn |
| kín | bín | rín |

| | | |
|---|---|---|
| ọkùnrin | ọkùnrin | ọkùnrin |
| ẹ̀bùn | ẹ̀bùn | ẹ̀bùn |
| ẹ̀rín | ẹ̀rín | ẹ̀rín |
| | | |

| | | |
|---|---|---|
| ọkùnrin | ọkùnrin | ọkùnrin |
| ẹ̀bùn | ẹ̀bùn | ẹ̀bùn |
| ẹ̀rín | ẹ̀rín | ẹ̀rín |
| | | |

Wọ́n dápẹ́ lọ́wọ́ bàbá.

Wọ́n dápẹ́ lọ́wọ́ bàbá.

Ó ra ẹ̀rọ-alágbèéká fún Tàlá.



Ọ̀rẹ́ kòríkòsùn ni Tárá àti Dára.
Ìpínlẹ̀ Ògùn ni wọ́n ń gbé.
Tárá ń lọ sí ìpínlẹ̀ Èkó.
Kí wọ́n tó pínyà,
Wọ́n gba nọ́ńbà fóònù ìyá wọn.

■ ÙN ùn ÍN ín

● pín sùn dín

▲ Ìpínlẹ̀ pínyà kòríkòsùn dínkù

★ Wọ́n gba nọ́ńbà fóònù ìyá wọn.

| | | |
|---|---|---|
| Ìpínlẹ̀ | Ìpínlẹ̀ | Ìpínlẹ̀ |
| kòríkòsùn | kòríkòsùn | kòríkòsùn |
| pínyà | pínyà | pínyà |
| dínkù | dínkù | dínkù |

| | | |
|---|---|---|
| Ìpínlẹ̀ | Ìpínlẹ̀ | Ìpínlẹ̀ |
| kòríkòsùn | kòríkòsùn | kòríkòsùn |
| pínyà | pínyà | pínyà |
| dínkù | dínkù | dínkù |

Kí wón tó pínyà.

Táró ń lọ sí ìpìnlẹ̀ Èkó.

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

ọn ÌN ÙN ÍN UN an

**Ìpín 2: Sílébù**

sùn kùn dún gun rìn yan

**Ìpín 3: rọ̀**

ọkùnrin ayanran kòríkòsùn mẹ́rin àgbọn ọ̀fìnkìn

**Ìpín 4: Àyọkà**

Tàlà nìkan ni ọmọkùnrin bàbá.
Bàbá fẹ́ràn Tárá ọmọ rẹ̀ kejì bí ojú.
Bàbá ra kọ̀ǹpútà ọmọdé fún Tárá.
Ó ra ẹ̀rọ-alágbèéká fún Tàlà.
Tàlà àti Tárá rẹ́rìn-ín.
Wọ́n dúpẹ́ lọ́wọ́ bàbá.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Kí ni orúkọ ọmọkùnrin bàbá?
2. Kí ni bàbá rà fún Tárá?
3. Kí ni ìdí tí Tàlà àti Tárá fi rẹ́rìn-ín?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

yangan ìròyì funfun yangan

**Àríwísí Olùkọ́:**

— Not for Sale —

PBYP1